**Ijọ́ Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu**
**Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà**
**ÌSÌN OMI MÁNNÀ**
**Kókó Àdúrà – ÌWÒSÀN PÍPÉ (7)**

**Ìjẹ́wọ́: Málákì 4:2:** Ṣùgbọ́n Òrùn òdodo yóò là, ti òn ti ìmúláradá ní ìyẹ́-apá rẹ̀, fún ẹ̀nyin tí ó bẹ̀rù orúkọ mi; ẹ̀nyin ó sì jáde lọ, ẹ̀nyin ó sì ma dàgbà bí àwọn ẹgbọ̀rọ̀ málù inú agbo.

**Orin Ìyìn àti Ìjọ́sìn**

1. Bàbá, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ fún agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
2. Mo lo ẹ̀jẹ̀ Jésù láti pa gbogbo gbòngbò àìsàn tó farasin nínú ayé mi run, ní orúkọ Jésù.
3. Mo wọ́n ẹ̀jẹ̀ Jésù sí àgọ́-ara mi, láti orí mi dé àtẹ́lẹsẹ̀ mi, ní orúkọ Jésù.
4. Mo ya gbogbo aninilara sátánì lárọ, tí wọ́n yàn lòdì sí àláfíà mi, ní orúkọ Jésù.
5. Mo di ẹ̀jẹ̀ Jésù mú gẹ́gẹ́ bí asà lòdì sí agbára òkùnkùn ìyówù tó n dá ayànmọ́ mi lóró, ní orúkọ Jésù.
6. Bàbá, jẹ́ kí gbogbo ilẹ̀kùn tímo ti ṣí sílẹ̀ fún ọ̀tá di títì pa títí láí nípa ṣẹ̀ ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
7. Nípa ṣẹ̀ ẹ̀jẹ̀ Jésù, a ti ràmípadà kúrò nínú gbogbo ìpọ́njú, ní orúkọ Jésù.
8. Nípa ṣẹ̀ ẹ̀jẹ̀ Jésù, ètò-ìṣúná mi gba ìwòsàn, ní orúkọ Jésù.
9. Nípa ṣẹ̀ ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo ní Ẹ̀mí Ọlọ́run nínú mi, ní orúkọ Jésù.
10. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, gé orí Gòlíátì tó n dàamú ayé mi sọnù, ní orúkọ Jésù.

11. Ohunkóhun nínú ayé mi tí kì í ṣe ti Ọlọ́run, jáde nípa iná báyìí, ní orúkọ Jésù.
12. Olúwa, jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ Jésù dúró sáàrín èmi àti àwọn agbára tí wọ́n yàn láti fàmílulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
13. Nípa ṣẹ̀ ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo gégùn fún gbogbo iṣẹ́ òkùnkùn nínú ayé mi kí ó gbẹ láti gbòngbò wá, ní orúkọ Jésù.
14. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, sọ̀rọ̀ ìyè sí gbogbo egungun t'óti d'òkú nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
15. Olúwa, jẹ́ kí a tú agbára ẹ̀jẹ̀ Jésù jáde nítorí mi, jẹ́ kí ó sọ̀rọ̀ lòdì sí gbogbo òkè olóríkunkun nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
16. Mo fa òbìrí ẹ̀jẹ̀ Jésù yímiká lòdì sí gbogbo ọfà ikú àìtọ́jọ́, ní orúkọ Jésù.
17. Mo borí gbogbo ẹ̀mí ìkùnà nípa ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́-Àgùtàn, ní orúkọ Jésù.
18. Kòsí ẹ̀mí, kòsí agbára tàbí ẹ̀dá tí yóò fi ohun búburú kankan sími lára mọ́, nítorí a ti ràmípadà nípa ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́-Àgùtàn, ní orúkọ Jésù.
19. Olúwa, jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ Jésù sọ̀rọ̀ ìdàrúdàpọ̀ sínú àgọ́ ọ̀tá, ní orúkọ Jésù.
20. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, gbẹ gbogbo igi búburú tí wọ́n yàn lòdì sí ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
21. Mo sọ gbogbo agbára búburú tó n gbógun dìde lòdì sí àláfíà mi di aláìlágbára nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.